ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN

# ALUBARIKA L'OJU (14)

**OLOTU, kara o le o! Gẹgẹbi asọti ọrọ wa na. Bayi ni awọn mejeji bẹrẹsi ki ara wọn pẹlu ọwọ ati apọnle. Baba yi si bọsi inu kẹkẹ ẹlẹṣin rẹ, o gbe ijoko nla kan jade, o si gbe ẹ fun ẹlẹha yi lati fi joko.**

Lẹhin ti Ẹlẹha na joko tan, ni baba na wa tọju onjẹ fun un. Ẹlẹha na si jẹun dada, ọkan rẹ si balẹ. Lẹhinna ni baba yi wa bere lọwọ Ẹlẹha na pe, "nibo ni ẹnyin ha ti mbọ wayi o? nibo ni ẹ si nlọ"?

ẸLẸHA SỌRỌ

Ẹlẹha na si dahun wipe, "Ọna ti a ti mbọ jinna pupọ, atipe, bayi-bayi si ni nkan ti o ti ṣẹlẹ si wa lojuomi lati nkan bi ọdun meje sẹhin. Ati pẹlu pe, lati igbana si wẹ, loni yi gan an ni mo to fi ẹsẹ mi kan ori iyẹpẹ ilẹ."

Ẹnu ya baba yi to bẹ ẹ gẹẹ, ti ko fi le sọ ohunkohun, o si tun bere wipe, "kini ẹ ha njẹ lati igbana? Atipe, bawo ni ẹ ha ti ṣe mun loju omi?"

Ẹlẹha na si dahun wipe, "eyi nṣẹlẹ pẹlu aṣẹ Ọlọrun nitoripe, lati ọjọ na, nṣe ni o dabi ẹniwipe ebi ki i pa mi rara, nitoripe, nigbogbo-igba, nṣe ni o ndabi ẹni wipe mo ṣẹṣẹ jẹun tan ni, nisisiyi ti ebi si ṣẹṣẹ nfẹ ma a pa mi na nimo de ọdọ nyin yi, ti ẹ si fun mi ni onjẹ."

ẸNU YA BABA

Nigbati baba na gbọ gbogbo alaye Ẹlẹha yi, ẹnu ya a pupọ, to bẹ ẹ ti ko fi te tun bere ohunkohun mọ.

Lẹhin eyi ni Ẹlẹha na wa bere lọwọ baba na wipe, "nibo ni ẹnyin ha nlọ bayi, atipe, nibo ni ẹ si ti mbọ?" Baba na si sọ wipe, lati erekuṣu kan ti ko ju bi irin ọjọ marun lọ ni on ti mbọ. Atipe, ilu kan ti o wa ni nkan bi ibuso mẹdogun si ibiti awọn wa yi ni on nlo.

O ni ilu na jẹ ilu nla, ati wipe ọja si ta ninu ilu na pupo to bẹ ẹ gẹ ẹ ti o fi jẹ wipe, ni gbogbo agbaiye ni nwọn ti nwọn ta ọja tabi ra ọja ninu ilu na.

Bi baba yi ti pari ọrọ rẹ yi tan ni Ẹlẹha na ba gba lati ba a lọ si ilu na. Awọn mejeji si palẹmọ ẹru wọn, baba yi si pese aye ibusun nla kan sinu kẹkẹ rẹ fun un.

AWỌN MEJEJI NLỌ

Ẹlẹha si bọsi ori ibusun na ninu kẹkẹ, baba paapa si gun ori ẹṣin ni iwaju kẹkẹ na, nwọn si bẹrẹsi lọ diẹdiẹ. Eti ebute odo



AKIBU ALARAPE

* * *

na ni nwọn si mba lọ titi ti ilẹ fi ṣu ni ọjọ na.

Ilẹ si ti ṣu pupọju ki nwọn to de ilu ti nwọn nlọ, to bẹ ẹ ti baba na ko fi le gbe kẹkẹ rẹ gba arin ilu nitoripe ọganjọ oru ti gan.

Baba na si pinnu lati fi kẹkẹ na silẹ ni ebute. O si dagbere fun Ẹlẹha pe, on nlọ kabọ na o, Ẹlẹha si da a lohun wipe, "ẹ ma pẹ o."

Bayi ni baba na ba forile ọna arin ilu na, o si lọ si Afin Ọba taara. Bi o ti de ẹnu ọna Afin Ọba ni awọn ọlọpa ba da a duro, nwọn si bere lọwọ re wipe, "nibo ni o gbe nlo?"

AFIN ỌBA

Baba na si ṣe alaye fun wọn pe, alejo ni on, atipe, on nwa aiye ibiti on le sun si ki ilẹ fi mọ ni. Awọn ọlọpa si mu baba na lọ si iwaju Ọba.

Ọba si pese ibugbe kan daradara fun un lati sun si mọju, ọba si tun paṣẹ wipe ki nwọn ṣe itọju rẹ dada, ki awọn fun un ni onjẹ ati omi lati mu ati lati fi wẹ.

Lẹhin eyi ni baba na tun ṣe alaye siwaju fun Ọba wipe, ẹru-ọja on, awọn ẹṣin ati kẹkẹ si wa ni eti-ebute, on si nfẹ awọn oluṣọ ti o to gbẹkẹle lati lọ ba on ṣọ ẹru na titi ti ilẹ yio fi mọ.

Awọn ẹmẹwa ọba si bere lọwọ baba na wipe, "iru ẹru wo ni ẹru re na ti o fi nwa oluṣọ ti o to gbẹkẹle lati ṣọ ọ nigbati o jẹwipe, ko si akuṣẹ tabi otoṣi kanṣoṣo ni gbogbo ilu wa yi jakejado, atipe, ko ti i si orilẹ-ede kan ti o ni dukia to ilu wa yi? Iru dukia wo ni o le gbẹkẹle ti o tun pọ ju ti ilu wa yi lo?"

IRANṢẸ ỌBA

Baba na si dahun wipe, "Họwu o! ọrọ yi mb'ọrọ miran? Nkan ti mo fẹ ki ẹ mọ ni wipe, ki iṣe wipe nipa ti dukia nikan ni mo nwa oluṣọ fun bikoṣe wipe arabirin olufọkansin-Ọlọrun tootọ kan ti o wa ninu kẹke mi si ebute.

"Nitorina ni mo ṣe nwa oluṣọ ti o ṣe e fi ọkan tan lati ba mi duro ti i titi di ilẹ mọ."

Nigbana ni ọrọ baba na wa ye Ọba na dada, o si kesi awọn olori-iranṣẹ-Ọba pe ki o ran awọn ọmọde meji tabi mẹta pe nwọn lọ duro ti ẹru baba onikẹkẹ na ni ebute titi ti ilẹ yio fi mọ.

Olotu, a dupe o Ọmọ-ọba nrele o, o digba.

Nikehin wayi

abẹ infarungbọn to mu julọ




Ọbe Alafẹfẹ NACET Ọlọni

Trade enquiries to: R. E. HARDING & CO. LTD • LAGOS • ABA • KANO

# 'IYAWO DUN LỌṢINGIN'





AWORAN ... [illegible]

[illegible]

**Akiyesi nipa oja Oja**

Ẹnikẹni ti o ba ri wipe awọn ojo oja wọnyi ko bọsi ọjọ ti nwọn ngna an, ki o kọwe si Olotu iwe 'Irohin Yoruba' fun atunse.

OLOTU





# Ọdun Eegun Isọlọ dun, o larinrin





AWORAN ... [illegible]

[illegible]


## Taji loju oorun Ki o si ṣ'ara giri!

Pẹlu ANDREWS LIVER SALT

[illegible]

ANDREWS TIO BAN O LOWO LATI YUN DI ARO-YUN' NI ONA META







ANDREWS LIVER SALT

# KADARA ẸDA (17)

## "Nipa igbagbọ ọkan ẹni ni a nku ti a si nye"

Lati ọwọ M. A. Akinbọade, Ibadan)

**NI ọsẹ yi, a o ma a ba ọrọ wa lọ lori awọn ofin atọwọdọwọ ati eewọ ilẹ wa ati ti ilẹ miran.**

Mo sọ ni ọsẹ ti o kọja wipe nigba kọọkan, omiran ninu awọn ohun ti a ko kasi wọnyi a ma a jasi "kọkọrọ" ti o le ṣi ilẹkun iderun fun ni bi a ba wa ninu iṣoro.

### IGBAGBỌ ỌKAN

Ohun ti mo fẹ ki ẹ gbagbọ ni wipe nipa igbagbọ ọkan ẹni ni a nku ti a si nye. Mo fẹ ki ẹ gbagbọ pẹlu wipe igbagbọ ninu awọn ofin atọwọdọwọ wọnyi ti bẹrẹ lati ọjọ awọn baba nla wa, o si ti dapọ mọ ẹjẹ wa lati iran de iran.

Nitorina ki iṣe ohun ti o rọrun funni lati sọ wipe bi a ko ba ti gbagbọ pe nkankan le ṣẹlẹ nkan na ko ni ṣẹlẹ. Fun apẹrẹ, bi a ba gbagbọ wipe gbogbo igbati a ba ṣeeṣi kọja labẹ akasọ ni iṣẹlẹ buburu yio ṣẹlẹ, ko si igba na ti a o kọja ni abẹ akasọ ti nkankan ki yio sele si wa



M. A. AKINBỌADE

Wayi o, bi eewọ yi ba jẹ ọkan ninu awọn eewọ orilẹ-ede wa, ohun ti a o kiyesi ni pe bi ẹnikan gbagbọ ninu rẹ tabi ko gbagbọ ninu rẹ, buburu ki yio ṣai ṣẹlẹ si i. bi o ba ru ofin na nitoripe ofin abinibi ni.

### IDẸKÚN EEWỌ

Njẹ bo ba jẹ pe nipa igbagbọ ti a ti bi ni mọ ti o si ti wa ninu ẹjẹ wa ni iṣẹlẹ buburu fi nṣẹlẹ nigbati a ba ru ofin atọwọdọwọ kan, a nilati ranti pe kosi eewo kan ti ko ni idẹkun.

Awọn ti nwọn gbagbọ gbagbọ ninu eewọ wipe bi a ba kọja labẹ akasọ ohun buburu yio ṣẹlẹ kanna ni nwọn tun sọ idẹkun yi wipe, afi bi enia ba gbe ika ifabẹla ati ọba ika ọwọ ọtun tabi ti osi leri ara won bi a ti nkọja labẹ akasọ na ni buburu ki yio ṣele

Nipa bayi, nigbati a ba kiyesi i pe kosi ọna miran niwaju wa ti a le gba bikoṣe ki a kọja labe akasọ ti nwọn gbe kalẹ ni oju ọna wa, a o wa gbe awọn ika wọnyi leri ara wọn, igbagbọ ti ika ti a gbe leri ara wọn yi ko ni jẹki buburu kan o ṣẹlẹ.

### ERO ATI IGBAGBỌ

Iru ero ati igbagbọ bawọnyi ni o sọ aimoye awọn enia di alawọṣe, ṣẹbọṣẹbọ, keferi ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ṣibẹṣibẹ awọn ti ko yapa jinna pupọ bayi, boya nipa jijẹ enia pataki tabi gbajumọ, tabi ẹniti ẹsin jinlẹ si ọkan wọn, ko ṣai ma a lo oriṣiriṣi nkan miran ti nwọn gbagbọ wipe o le ran awọn lowo lakoko iṣoro.

Ni gbogbo orilẹ ede ni a ri awọn ọlọla ati enia pataki-pataki ti nwọn gbagbọ ninu oriṣiriṣi nkan ti nwọn ko si fi igbagbọ wọn pamọ rara.

Alakoso Ijọba Iwọ-Orun ilẹ Jamani ti a npe ni Adenauer ni a gbọ wipe o korira ọjọ Jimọ (Friday) pupọ, ko si jẹ dawọle ohunkohun lati ṣe ni ọjọ yi.

Bakanna ni a gbọ wipe Ọbabirin ilẹ Gẹẹsi ti a npe ni Elizabeth Keji ko jẹ ṣe ohun pataki kan ni ọjọ kẹtala (13) ati ẹkẹtadinlogun (17) oṣu koṣu.

### AWURE IṢỌRA

Ogunlọgọ awọn olowo nlanla (milọnia) ilẹ gbogbo ni nwọn ma a nlo oogun ti a pe ni Talisman fun awure tabi iṣọra, ṣugbọn awọn miran fi ilo nkan wọnyi pamọ.

Igbagbọ ninu agbara awọn Irawọ lori Kadara wa ki iṣe ajeji mọ si awa enia dudu, bakanna ni igbagbọ ninu itumọ awọn ọjọ ti o mbẹ ninu ọsẹ. Awọn enia si gbagbọ pẹlu ninu nọmba pẹlu itumọ wọn.

Mo ti fi ẹnu kan ti awọn Irawọ lẹẹkan bi ẹ ko ba gbagbe, ṣugbọn bi a ti mba ọrọ wa lọ yi ngo tun awọn alaye na ṣe fun nyin ni kikun.

Bayi ni a kiyesi i wipe igbagbọ ninu agbara ajẹ, oogun buburu-gbogbo l'oriṣiriṣi ati awọn ofin ati eewọ abalaiye yioku lẹ ohun ti a fi ẹjẹ rẹ bi ẹda, bakanna pẹlu si ni awọn ohun idẹkun ti o nfun ni irọrun tabi "igbala" ninu iṣoro nipa igbagbọ ti a ni si wọn.

A o ma a ba ọrọ wa lọ o.

Alafia fun nyin o.


Ki ọpa-ẹhin le tọ-rọrọ ki tapa-titan si lagbara dada FUN ỌMỌ RẸ NI




OSTERMILK

Ile iṣẹ egbogi Glaxo Laboratories Ltd., Greenford, England ni o nṣe e

Awọn alagbata rẹ ni GLAXO-ALLENBURYS (NIGERIA) LTD. P.M.B. 2910. Lagos ati nole ni ABA ati KANO


***Ẹ ma a ka Iwe* IROHIN YORUBA *nigbagbogbo fun irohin aladun***

A KO le ṣe alaidupẹ gidi-gidi lọwọ awọn Ijọba orilẹ-ede wa ti nwọn ngbiyanju lọnakọna lati mu alafia wa si orilẹ-ede na.

Nibi gbogbo ni a ti ngbọ loni ti awọn olori oṣelu wa ti nke fun alafia ati iṣọkan ninu orilẹ-ede gbogbo, ti nwọn ko si simi lati ri pe nwọn mu alafia ati irọrun wọ ilu wa fun gbogbo enia. Nitori idi eleyi ni a ṣe ni orişirişi awọn oşişẹ ni igboro ilu ati awọn ileto kakiri loni.

### AWỌN ALAABO WA

A ni awọn ọlọpa ti nwọn ndaabo bo wa nigbati ewu ba de ti nwọn si ma a ngbiyanju lati mu alafia wa sinu ilu. Awọn Ọmọ-ogun bakanna wa fun aabo ati ipamọ ilu kuro lọwọ awọn orilẹ-ede miran ti nwọn ba fẹ gbe ogun ti wa.

A ko si le gbagbe awọn ọmọ-ogun oju omi ti nwọn nfi igbagbogbo ṣọ etikun nitori awọn ọta ti nwọn yio fẹ lati gba ti oju omi wọ ilu.

Ni ipari gbogbo rẹ ni a ti tun yan awọn kan lati

# Akede Ọna Igbala

# Ẹ MAA LEPA ALAFIA

joko ṣe idajọ awọn enia ti nwọn ba fẹ da alafia ilu ru, ki nwọn le ṣe ohun ẹtọ lori wọn. A nṣe awọn ohun gbogbo wọnyi lati mu alafia ati irọrun ba orilẹ-ede wa.

### ILEPA ALAFIA

Ọrọ Ọlọrun ni o sọ wipe ki a ma a wa alafia ki a si ma a lepa rẹ. Awọn Ijọba na nṣe agbara ibiti nwọn le ṣe ki alafia ba a le wa larin awọn enia gbogbo, şugbọn ibere mi ni pe, njẹ alafia na wa bi? Ko si alafia. Kaka ki o ri bẹ, iyọnu na npọ siwaju si i ninu aiye loni.

Ni aipẹ yi ni a gbọ iye awọn enia ti nwọn sọ ẹmi wọn nu ninu ija igboro ti o bẹ silẹ ni isalẹ ilẹ enia dudu ( South Africa), ti nwọn npa ara wọn ni ojojumọ bi ẹni pa ẹran. Tabi ko si ọlọpa nibẹ ati awọn Ọmọ-ogun ti o le ṣe iranlọwọ lati da iru rogbodiyan wọnyi duro ni? Awọn orilẹ-ede wọnyi na nwa alafia fun ara wọn ni iru ijọngbọn nla yi ṣe bẹrẹ larin wọn.

Kini o fa iku Ologbe Patrice Lumumba, ẹni ọwọn, akikanju, alakoso ekinni fun ilẹ Kongo? Ko ha ṣe alafia orilẹ-ede rẹ ni o nja fun? Ainiye awọn ọmọ-ogun lati orilẹ-ede aiye ni nwọn ti ran lọ si ilẹ Kongo lati ran wọn lọwọ kuro ninu wahala ati lati mu alafia wa si arin wọn.

Şugbọn sibẹsibẹ ojojumọ ni awọn enia nku bi adiẹ ti nwọn ko si daro fun ẹmi ara wọn, bi ẹlẹkun ti nsunkun bẹni onigede npe igede ti gbogbo orilẹ-ede ilẹ Kongo si daru lati oke de isalẹ.

### ỌNA KANṢOṢO

Njẹ gbogbo awọn iranlọwọ wọnyi ha mu alafia wa fun ilẹ Kongo bi? Ki işe bẹ nitoripe ija şi ntẹsiwaju larin awọn enia na titi di bi a ti nsọ lọwọ yi.

Ọna kanşoşo ti a ti le ri alafia ni ọdọ ẹnikan na ti O wi fun awọn ọmọ-ẹhin Rẹ ni ọjọ wonni pe, "Alafia fun nyin," a ni Jesu Kristi nitoripe ọdọ Rẹ nikan ni alafia, itẹlọrun ati ayọ ti ko lopin wa.

A gbọ ninu Ọrọ Ọlọrun ti o ka fun wa bayi pe, "Njẹ bi a si ti nda wa lare nipa igbagbọ, awa ni alafia lọdọ Ọlọrun nipa Oluwa wa Jesu Kristi;" (Romu 5: 1)?

Esẹ Ọrọ Ọlọrun yi nfi ye wa kedere pe ko si ọna miran t'a le fi gba ni alafia ni igbe-aiye wa bikoṣe nipasẹ Jesu Kristi ẹni ti iṣe onilaja wa larin Ọlọrun. "Nitori Ọlọrun kan ni mbẹ, Onilaja kan pẹlu, larin Ọlọrun ati enia, on paapa enia, ani Kristi Jesu " (1 Timoteu 2: 5).

### AWỌN ONILAJA

A nran awọn ọmọ- ogun lati lọ fi alafia si arin awọn meji ti nja, şugbọn nigbati nwọn ba de oju ija na tan awọn na a ma a bẹrẹ si jadu ẹmi ara wọn, nwọn a si kọju ija si awọn ti o nja lati ma a ba wọn ja dipo a ti la wọn ni ija.

Awọn onilaja aiye yi ni ẹniti a ni ko kin wa lẹhin ti nwọn fi ẹgun sọwọ, ti a ni ki nwọn fẹ wa loju ti nwọn fi ata senu. Şugbọn ti Jesu Kristi Ọmọ Ọlọrun ko ri bẹ nitori igbagbogbo ni O duro niwaju Ọlọrun Baba ti O si mbẹbẹ fun idariji ẹsẹ awa enia Rẹ.

Awọn ẹlomiran ro wipe nigbati awọn ba ni owo ni awọn nlepa alafia, awọn miran ewẹ nro nipa ti ọmọ, awọn miran si nro nipa ẹkọ.

Şugbọn asan ni awọn nkan wọn yi jẹ fun wa lai ni alafia ninu Jesu Kristi, nitori ọpọ awọn olowo, onipo nla, ẹlẹkọ ijinlẹ ati

> "Ọna kanşoşo ti a ti le ri alafia ni ọdọ ẹnikan na ti O wi fun awọn ọmọ ẹhin Rẹ ni ọjọ wonni pe, alafia fun nyin".

ọlọmọ pupọ ni nwọn wa loni ti nwọn ko ni alafia ninu ọkan wọn, itẹlọrun si jinna si ọdọ wọn bi sanma ti jinna si ilẹ.

### IYE AINIPẸKUN

Nitoripe ki i ṣe ọna alafia ni nwọn nrin, bẹni nwọn ko si le gba ọna na de inu iye ainipẹkun.

Şugbọn loni, Jesu nwipe, "Ẹ wa sọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nşişẹ ti a si di ẹru wuwo le lori, emi o si fi isimi fun ọkan nyin, nitori ajaga mi rọrun ẹru mi si fuyẹ" (Matteu 11: 28).

Ẹ wa si ọdọ Ọlọrun nipasẹ Jesu Kristi nibiti iwọ yio ti ri iye alafia fun ọkan rẹ. Wa alafia na nigbagbogbo ninu Jesu Kristi. Ma a wa nipa gbigba oruko iyebiye na gbọ, Jesu Kristi ẹniti o tan gbogbo arun rẹ ti o si fi ogo ati ọla de ọ il ade ni iku Rẹ lori igi agbelebu fun imu kuro ẹsẹ rẹ.

"Ma a wa alafia, ki o si lepa rẹ" (Orin Dafidi 34: 14).




# ALAPARA

(Lati oju ewe kẹta)

owo-ijẹun ti o wa lọwọ mi ni nwọn gba lọwọ mi lẹhin ti nwọn ti lu mi tan, ti nwọn si ti sọ mi di olokunrun, ohun ti ko jẹki nwọn ri owo pupọ gba lọwọ mi ni pe, mo ti gbe owo ti mo fi nşọwọ pamọ si Ibadan, mo şebi ma a ri ọja ra ki nwipe ki obirin na wa ya mi lowo ni.

OLOTU—Şe o ri obirin na nigbati ilẹ mọ?

ALAPARA—Olotu, ki a sa fi ọrọ na mọ bẹẹ, mo ri i nigbati ilẹ mọ, o ni on ngbọ igbe mi ti mo nkesi on ni oru, şugbọn alejo wa lọdọ on nigbana.

OLOTU—O ko bi i lere pe iru alejo wo ni?

ALAPARA—Ka sa fo o, tani a ri bawi, bi emi ti mo to ẹwu u wọ, ti mo nso aşọ kọ. Ẹ jowọ, mo şi nlọ na mo fẹ lọ f'aarẹ si ile. Ẹ ko ni pẹ ri mi o digba o.

OLOTU—Kabọ o, oju ko fẹra ku o, ipade wa bi oyin, Alapara kọja aye rẹ "Baakodaya"!

ALAPARA—Bẹni o Olotu, mo kọja aye mi



ALAPARA IBADAN

